# Ṣe ki n gbe ọ dìde lori nnkan ti ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- gbe mi dìde lórí ẹ? Ma fi ère kan kan silẹ àfi ki o pa a rẹ, ma si fi sàréè ti o ga kan kan silẹ afi ki o jẹ ki o bá ilẹ̀ dọ́gba

Lati ọdọ Abu Al-Hayyaaj Al-Asadiy, o sọ pe: Aliy ọmọ Abu Tọọlib sọ fun mi pe: Ṣe ki n gbe ọ dìde lori nnkan ti ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- gbe mi dìde lórí ẹ? Ma fi ère kan kan silẹ àfi ki o pa a rẹ, ma si fi sàréè ti o ga kan kan silẹ afi ki o jẹ ki o bá ilẹ̀ dọ́gba.
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa n ran àwọn saabe rẹ pe ki wọn ma fi ère- oun ni aworan nǹkan ti o ni ẹmi ti o jẹ abara tabi eyi ti ko ni ara- kan kan sílẹ̀ afi ki wọn mu u kuro tabi ki wọn pa a rẹ. Ki wọn si ma fi sàréè ti o ga kan kan sílẹ̀ ayafi ki wọn jẹ ki o ba ilẹ̀ dọ́gba, ki wọn si wó nǹkan ti wọn kọ́ sori ẹ, tabi ki wọn ṣe e ni nǹkan ti o maa tẹ́ pẹrẹsẹ ti ko nii ga nílẹ̀ pupọ, ṣùgbọ́n o maa ga ni odiwọn àlàáfo ti o wa laarin ìka àtàǹpàkò ati ika ọmọndinrin.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee